# ELETI ỌFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LEJỌ'

VOL XIV NO 925 LAGOS SATURDAY JUNE 13— JUNE 19 1964 KỌBỌ MEJI (2D)


ELEYI ARA !

# Awon Elewon Nferan Enia S'obe Ni Ilu Jamani

FRANKURT—Ni ọjọ Iṣẹgun t nṣe ọjọ kẹsan oṣu yi nị ilu Aushwitz nị ilu awọn Oy nbo Jamani ni ịrohịn kan wa wipe awọn ẹlẹwọn kan ti nwọn nṣịṣẹ ni ịle egbogi fun ịmọtoto (Laboratory of t h e Instituto of Hygiene) se ẹran enia jẹ lati fi mọ boya o le ko arun ba enia gẹgẹbị ẹkọ ti nwọn nkọ. Ẹlewọn kan nị o tu aṣịrị yị nigbati nwọn pe e lati jẹri si awọn kan ti nwọn mba sẹjọ apania ni iwaju adajọ kotu nla ilu Jamani.

Ọgbẹni Imrịch Goenezị, ẹni ọdun mọkandilogoji ti o je wipe iṣe yọhin-yọhin (Dentist) nị o nṣe latị ilu Czehoslovakia wa kị awọn to mu u tịmọle tịtọ si tun jẹ ọkan ninu awọn oṣ ṣẹ ninu ịle egbogị na ni nwọn fun awọn nị ẹran lati fi sịsẹ ṣugbọn b o y a ẹran ẹṣịn ni tabị ẹran gaan ni eyiti awọn ni l a t ị bọọ daradara lati le mu ororo jade lara wọn atị pe lẹhịn ti awọn ẹran na ba ti jina tan awọn tị awọn si jẹ ẹlẹwọn ni latị pịn awọn ẹran na jẹ larin ara wọn.

Ọgbẹni Goenczi tun sọpe nị ọjọ kan nw ọ n fi idẹ-omị olokuta meji ko awọn ẹran kan wa f u n awọn on si ri wọn d a j u wịpe nwọn kii se ẹ r a n eṣin ni yio wa ninu wọn tabi ẹran toto idi eyi ni on fi t ọ ọga agb awọn lọ tị orukọ rẹ njẹ Tomascheok ti on n a tun je ẹlẹwọn bi awọn on si sọfun pe ẹran enia ni o wa ninu awọn idẹ na.

Ọgbẹn G oenczị lo sọ ọrọ nwọnyi nịwaju adajọ nịgbatị o njẹri ninu ẹjọ ti Ijọba m b a a w ọ n enia mọkanlelogun kan ṣe lori ẹsun ipania o sị tun ṣe alaye pe on g b a g b ọ pe awọn kan ti a npe ni oṣiṣẹ SS (SS men) ni nwọn fi ẹran enia rọpọ ẹran ẹsin atị ẹran t o t ọ ti nwọn ti fipamọ lati jẹ fun ara wọn.

## Obirin Kan Bi Alujonu Omo

LỌKỌJA - Gbogbo awọn ara ilu nị nwọn nsare lati wo ọmọ abami kan ti nwọn bi si ile igbebi Ijọba ni oṣu ịto kọja ni Lọkọja, ọmọ alalujọnu na wọn ju ẹsun mẹfa iwọn lọ, lọjọkanna ti nwọn bi i, ko si kegbe rara.

Ọmọ na ni oju meji ni ọkọkan iwaju ori rẹ, ṣugbọn gẹgẹbi irohịn lati ọdọ awọn dokita ẹgbẹbi-ọmọ ọmọ na ṣi wa nị itọju wọn fun ero lori iru ona ti awọn yio gbe tị ọmọ alagbako na gba.

# Awon Osise Ta'ku Mo Ijoba Lowo

Ju gbogbo re lọ ogunlogo awọn oṣiṣẹ ti nwọn da iṣẹ silẹ ti taku patapata mọ Ijọba lọwọ; nwọn ni awọn ko ni pada sẹnu iṣẹ awọn titi ti awọn alakoso Ijọba Apapọṣe yioṅ sọ ṣako nkan ti nwọn ba ro lori ẹkunwo ti Morgan ni ki nwọn fi kun owo oṣu awọn.

A gbọ wipe o ti to ẹgba a marun (10,000) awọn oṣiṣẹ Ijọba ti nwọn ti ba ni iwe wipe ki nwọn wa sọ akan ti o fa a ti awọn ko fi ri wọn nibi iṣẹ wọn.

Nwọn ni Ijọba fun won laye di owurọ ijẹta Ọjọbọ (Ọjọ Alamisi), ẹniti awọn ko ba ri kowa berẹ iṣẹ rẹ, awọn yio daa duro.

Gbogbo awọn oṣiṣẹ ti nwọn lọ ṣe ipade ni Idi Oro ni irọlẹ ijẹta ni awọn faake kọri wipe ki awọn da awọn duro, ebi ko ni pa awọn soju ita-gbangba.

IRỌ NI NWỌN NPA:

## Aja Olopa Ko Gbowo Osu L'Eko

EKO—Fun irọ kan ti awọn oṣiṣẹ ti nwọn da iṣe sile npa kiri lori Aja ti awọn Olọpa fi asọde, awọn ọga ọlọpa ti tutọ soke, sọpe, nwọn ti foju gba a wipe ọrọ arosọ ni wipe Ijọba nsan pọn un mẹdogun fun aja kọkan loṣoṣu.

Awọn ọlọpa ni ọrọ na ko boju mu rara. Bi enia yio tilẹ parọ a ro o diẹ ki o to pa a. Ẹranko ni aja; bawo ni enia ṣe le sanwo oṣu fun Eranko?

Ninu iwe alaye ti awọn Olọpa gbe jade lati ile iṣe wọn ni Ọbalende l'Eko, nwọn ni ko ju pọnun mẹrin tabi pọnun mẹfa lọ ti awọn na lati fi bọ aja kọkan loṣu lọ.

Nwọn ni iṣe awọn aja olọpa na kọ yoyọ, nitori pe lati igbati awọn ti ko wọn wọlu ni awọn ti sakiyesi wipe awọn ole ti nlọ ile loru.

## Agbawo Kan Jegun Obinrin Oga Re

LONDON — Nwọn ka iwe-ogun kan fun Oyinbo agbọti kan, Stanley Cozens lana wipe ọga rẹ obinrin kan ti o ti nsịn lati iwọ nkan bi ọdun mọkandịnlogun fị ẹgbẹ mẹdogbọn pọnun (£50,000) silẹ fun un ninu owo kan ti obinrin na, Iyaafin Dorothy Sundy ti o jẹ laisi

((Wo iyoku loju ewe kejọ)

# Omo Egbe Olope Da Ijangban Sile Ni Remo

REMO—Ose to koja lo je ojo buruku esu gbomimu ni Sagamu ti ijo olu ilu Remo ni Ijebu-Ode n gbati awon janduku igbarauu awon omo egbe olope da ijangban sile, ti nwon nwon ile onile, ti nwon nko oppolopo ohun ini eni-eleni, ti awon si tun ntinabele onile ni ojo ti nwon lo pade Dokita M I. Okpara, Olotu Ipinle Ijoba Ila Oorun, awon si tun ba opolopo moto je pelu.

Nina awon moto ti nwon baje ni awon wonyi wa—WK 2030 ti nse ti ogbeni A. Oyekoya WR296 ti se ohun ini ti Alhaji Adegbi e alaga egbe Demo ni Sagamu R 8880 moto ti ogbe ni D. S. D. Oladeinde, eniti o ni ile gbe ojosepo (Social Club) ni ilu Ibadan awon ti nwon ti padanu ohun ini won julo ni awon omo egbe Demo ti nwon si tun ba moto ati ile won je lopolopo bi WAL 435, moto alajapa oju ona (Volks Wagen) ti egbe Demo, ile ogbeni Amusa Lawal ile Alhaja Ade Saadatu e ti nwon dabasun, ile ogbeni E. O. Osunrea, ile afe kan ti nwon npe ni Holly wood Bar ti nse ti ogbeni Jimo Aketedolu, ati ile oludamoran kan (Councellor) ogbeni Eniola Odunayo pelu gbogbo ohun ini re.

Ni kete lehin ti rogbodiyan na losile, oba Okewu Iji ti ilu Okunowo nso fun onirohin wa kan ejo ngboro wipe on sakiyesi wipe nwon ti ji ewu oye okan ninu awon ijoye on lo ati pe on si ti fi oro na si eti igbo Oba Akarigbo ti ilu Remo sugbon sibe, ko [illegible] oro ooi.

Awon janduku igbarefu na tun lo si gbongan ile ipade awon Igbimo ilu Makun, nwon si tu gbogbo igbimo na ka, gbogbo eleyi sele ni ojo Eti (Friday ati ojo Abameta (Saturday) ti ise ojo karun ati ikefa osu kefa odun yi. Ni ojo Aiku (Sunday) ti ise ojo keje osu yi ni Dokita M.I. Okpara lo be Oba Akarigbo wo, ki o to de safin ni gbogbo ojude Oba ti efe ie'e tun asia ati awon ohun meremere ti nwon fi se ibe loso, ilu rdun bena ijo si nlo ielu sugbon ohun to tun nyanilenu ni wipe awon janduku egbe O'ere lo be awon omode lowe, ti ojo ori won ko ju odun medogun lo, ti nwon si ko ada ati kumo lowo ti si ntowo kakiri ilu Ofin ati Makun.

Lori gbogbo rogbodiyan yi, awon olopa ko tile jigiri tabi ki nwon tile gbero lati mu awon janduku wonyi tabi lati tu won ka. Onirohin wa fi nye wa pe ni ilu Ipara awon [illegible] enia ipelu ibon lowo won ni awon lo sapamo sinu igbo ni ero lati yinbon pa Omo Oba Adeleke Adedoyin Asoju ti ile Igbimo Ipinle Iwo Orun eniti nwon ni ireti pe on yio pada si Ibadan ni ojo Aiku ti nse (Sunday) ti o koja, sugbon titi di isisiyi ko si irohin wipe isele buruku kan be sue lori omoba Adeleke Adedoyin.

A tun gbo pe lehin ti gbogbo hila-hilo na lo silo tan, awon Iko ri Oba Akarigbo lati ba soro, beni awon obinrin ti mbe ninu aafin Oba si dahun pe ko si aye fun Oba rara lati gba alejo kankan.

Okan ninu awon Asiwaju Egbe Demo ati yeni pe esun nipa iwa adarugudu sile yi ni awon mu wa siwaju awon olopa ti Naijiria, sugbon nwon ko lati se nkankan nipa re.

# Egbe Demo Se Ipade L'Eko

Lati Owo Rafiu Popoola

EKO— Ojo kejidinlogbon osu karun odun yi je ojo kan ti o lareneu pupo ninu, l'ode ati niwaju gbangan ile aworan alalupayida ni Offin, (Rialto Cinema) ni Eko nigbati awon omo Egbe Demo se ipade nla kan, enia ti nwon wa si ipade na si to bi edegbeta.

Irohin ko to afojuba ni ipade na je, nitoripe opolopo ninu awon omo egbe miran ati awon ti won ko ti wo egbe kan ti ni nwon fi oruko sile lati di omo egbe Demo lati adugbo Olowogbowo titi de Offin, nwon si se ileri tokantokan wipe awon yio tele ilana ati Offin egbe Demo ati lati sise taratara fun idagbasoke egbe na ni igboro ilu Eko.

Opolopo ninu awon enia titun ti nwon faramo egbe Demo ni ojo na ni yeni wipe kosi ohun meji ti o mu awon faramo egbe yi ju pe o je egbe olododo, egbe egbe igbala, ati egbe imole pelu nitoripe ninu egbe ti awon ti nse teleri, awon ko ri ere tabi anfani kan nibe, lehina, gbogbo ohun ini won lo tan sibe patapata.

Oloye Fagbenro Beyioku ti nse Asiwaju egbe Demo ni ilu Eko ati agbegbe re je akikanju enia, Oloyelori ati oselu pataki eniti o mu ki egbe Demo lu jade ki o si ni gbongbo ati eka dupo kakiri ilu Eko.

Alaga ipin A4 (Ward A4) Ogbeni Tajudeen Thompson ti egbe Demo ni adugbo Olowogbowo si tun je okan ninu awon igi lehin-ogba fun idagbasoke ati ilosiwaju egbe Demo, on na si so ileri lati se iranlowo fun awon omo egbe ni apakaye to ko si sile fun ise sise.

Oro iwuri ti poju lotun-losi lati enu awon Olotu egbe na, eyiti o nfi hanmi daju pe Demo ndagba-oje, ile si su ki ipade na to tuku.

E ka oro Ikose Akonije

( Loju ewe 'karun )

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin

ELETI—OFE

ti o kun fun irohin aladun losose.

# Irohin Eto Ikose Akonije Nilu Oyinbo

Lati Owo Adeymi Adekeye
(AKOWE AWON OMO ONISE IWE-TITE NI NIGERIA)

Ninu ẹkọ ajumọ kọ fun awọn ẹgbẹ ati oṣiṣẹ atẹwe ni gbogbo agbaiye fun ilọsiwaju ninu iṣẹ wọn eyiti nwọn ṣe ni Olu ilu Gẹẹsi (London) lẹnu lọlọ yi, ogun awọn akẹkọ lati orisirisi ilu ni agbaiye ni nwọn wa sibẹ ti nwọn si ti ṣe aṣeyanri ẹkọ na patapata.

Ọpọlọpọ ni o wa lati ile Enia dudu. Awọn meta wa lati ilu Nigeria, ẹnikansoṣo lati ilu Saro, meji lati Ariwa Rhodesia ẹnikan lati Tangayika pẹlu Uganda ati Swanziland.

Ninu awọn mẹsan ti o ku ẹnikan wa lati British Guiana meta lati Ceylon ọkan lati Cyprus, Gibral- ati mẹla lati Malaya. Nipa bayi a ri wipe gbogbo awọn ilu ti nṣe eto Ijọba wọn fun ara wọn ni nwọn yan akẹkọ wa sibi ikọṣẹ akọnijẹ na patapata.

Awọn olotu pataki mẹta nipa lọsiwaju ṣiṣẹ iṣẹ ni ilu Gẹẹsi ni o ṣe eto ẹkọ na. Ek ni nibẹ ni awọn oṣiṣẹ fun kikọ awọn akẹkọ lati ilu okerẹ nisẹ, ti o wa labẹ aṣẹ alabojuto nipa iṣẹ s ṣẹ, ẹkẹta si ni ẹgbẹ ti o nṣe eto ẹkọ fun iṣẹ erọ s ṣe apapọ agbaiye ni ilu Gẹsi ti nwọn si ṣ'aya gbangba lati ṣe inawo fun atijẹ pẹlu atimu awọn akẹkọ n lati ilu okere wa.

Iru eto ẹkọ ajumọkọ yi ti bẹrẹ lati ọdun meje sẹhin wa lati fikun lakaye awọn ẹgbẹ ti nwa alafia awọn oṣiṣẹ fun idagbasoke ninu iṣẹ wọn, ati wipe awọn akẹkọ wọnyi ni a ti van wa nipa aṣẹ awọn Ijọba ti nṣe agbelẹṣẹ fun ẹgbẹ wọn.

Iou mi dun lati sọpe mo jẹ ọkan ninu awọn akẹkọ na, gbogbo akoko ti a si wa ni ilu Gẹẹsi je asiko ti o nigbadun pupa ti o si wunilori pupọ fun orisirisi nkan meremere ti o fun ni ọgbọn ati lakaye pẹlu a si tun kọ pupa nipa ilana ati oye ti a ngba fi ṣiṣẹ akọnijẹ fun awọn ọmọ ẹgbẹ oṣeṣẹ ni ilu Gẹsi.

Ninu awọn ẹkọ patki ti a kọ ni lati mọ iru ẹkọ ti awọn aṣiwaju ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ nlo fi ṣe wọn lati maa wa anfani ati idẹra fun awọn oṣiṣẹ pẹlu ilera wọn, wiwa ni irẹpọ ati iwa bi ọlọrun ati nipa bibere owo ti o lẹtọ si awọn oṣiṣẹ lati ọdọ ijọba.

Lẹhin ti a pari ẹkọ wa ta a wa ni simi diẹ lati tun mu gbogbo nkan ti a

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

## Awọn Danadana Da Baba Elepo Moto Lona Sosi

IBADAN — Awọn danadana merin kan ti awọn Ọlọpa ru wa si kotu Ọlọpa ni wa ... ti Ọlọpa ni Oriṣẹ ni ... pẹlu ẹsun wipe awọn dabo unrin ka Thomas Awobiyi ti o nta epo moto ... nigbati nlọ si Ṣọṣi, nwọn si ja pọun mẹdọgbọn (£25 gba lọwọ rẹ.

Awọn ẹdaran na ni Musa Paro, Bello Ajao, Ayinla Buroimọ pẹlu Afọla a George. Awọn ọlọpa ti bẹrẹ si ro ẹjọ wọn sugbọn wọn ni ki adajọ ma gba iduro fun wọn.

Awobiyi ti nwọn ja owo na gba lọwọ rẹ ... o kọ ro ẹjọ ni iwaju adajọ o ni ki on to gba ọna Ṣọṣi lọ iọjọ na ... iṣẹ ti nwọn ti mba on ta epo moto ri on kọ lọ lati lọ gba owo ti nwọn pa silẹ fun on.

O ni boya awọn arufin na ti nṣọ on ni, on ko mọ, sugbọn ojiji ni on ri ti awọn yi on ka, ti Olori wọn ti nwọn npe ni Sunday ni ki nwọn ma gba on loju.

Waraweren wọn ti bẹr si ko awọn nkan ti o wa lapo on jade. Awobiyi ri wọn ṣe Ọgbẹni alanu kan ti o njẹ Smart Okomedo ti o fẹ gba on silẹ lọwọ wọn ni ijamba, nwọn si fi igo fọọ lori.

Awobiyi ni awọn merin ti awọn Ọlọpa ri ko ninu awọn marun ti nwọn da on lọna niyi; Olori wọn ti nwọn npe ni Sunday ti salọ.

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

Fun ina didá ati fun imọle
BP SUPERLITE KEROSINE
L'ayo!




Ti o ba sọpa Kerosine lo fe BP Superlite l'ayo o le si ra nibikibi, ko si wọn, o mọ daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, ina-titan ati lati mu fi yana Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

# Eleti—Ofe D'araba

# ELETI-OFE
(A NJE WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME

28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 925 SATURDAY June 13 — June 19 1964


## ORO OLOTU

# Nipa Awọn T'o Da Iṣẹ Silẹ

Ọrọ awọn oṣiṣẹ wa ti nwọn ea iṣẹ silẹ lati b! ọsẹ keji sẹhin ti a fẹ fẹnu kan ninu iwe irohin wa lọsẹ yi gọ'ẹge pupọ, ko si fẹ ṣe e ni ọrọ ọrisa bi o ko ba le gba mi, ki o ṣe mi bi o ti ba mi.

Nitotọ ọna ọfun, ọna ọrun ni; lori ọrọ ọmọlẹbi ti Ọlọla Tafawa Balewa tiṣe Alakoso Ijọba Apapọsẹsọ ninu ẹrọ gbohungbohun ni arin ọsẹ yi wipe ki gbogbo awọn oṣiṣẹ na pada ṣẹnu iṣẹ wọn ki awọn le mọ eyi ti awọn (alakoso Ijọba ilẹ yi) yio ṣe si iwe ti awọn gbe jade ti awọn oṣiṣẹ ni ko tẹ awọn lọrun ni yi yio jẹki awa na ba wọn damọran wipe ki nwọn pada sẹnu iṣẹ wọn.

Agbọrandun awọn ara ilu ni awa onive irohin jẹ lọjọkọjọ a ko si le sọ wipe awa na ko mọ wipe rere nrun lara awọn osiṣẹ ti ngba owo lọṣọsu sugbọn egun otolo ni o yẹ ki a fi to nkan ti o wa nilẹ yi.

Boya ẹ le wipe ṣebi Ijọba ni e mba ja, ọrọ yi ko kan awọn ara ilu rara. Ki o ma ṣi wa ye, ẹnika kii jẹ Ijọba ju awọn awọn ara ilu lọ. Ọrọ ti o de ilẹ yi ko kan Oloye Modupẹ Johnson tabi Ọgbẹni Jacob Ọbande rara. Afunisọ ni gbogbo wọn jẹ fun awọn ara ilu patapata iranṣẹ wa si ni nwọn nṣe.

Bi ojo ba kọ ti ko rọ oju gbogbo olọko ni yio ja. Bi awọn osiṣe ba ko jalẹ ti nwọn ko pada sẹnu iṣẹ wọn lasiko gbogbo awọn ara ilu ni yio mọ ọrọ na lara nitoripe awọn ti nwọn ngbe ile onigba ojule ni Ikoyi ti ṣeto anfani fun ara wọn ti awọn ara ilu nikan loku.

Lẹkansi, a bẹ ẹnyin oṣiṣẹ ki ẹ pada sẹnu iṣẹ yin ki e le reju raye jiroro lori owo ogun oju yin. Ọna ọfun, ọna ọrun.

# Iwe Si Olotu

# Enyin okawe wa

Boya ọpọlọpọ iwe ni ẹnyin ọkawe wa ti ko si wa lati ọjọ mẹta wa, anu ṣe wa lati sọ fun yin wipe awọn iwe na ko tẹ wa lọwọ rara nitoripe awọn ojiṣẹ Ijọba ti nwọn nha iwe kakiri ti ju iṣẹ silẹ lori edeaiyede ti o wa larin wọn pẹlu awọn oniṣẹ wọn.

Ntorina a tọrọ af rijin lọwọ yin, ki ẹ ma binu ti ẹ ko ba ri i ki a tẹ awọn iwe ẹdun ọkan yin (ti ẹ kọ si OLOTU ELETI-ỌFẸ) ni ọsẹ yi tabi ni ọsẹ ti mbọ.

A si fẹ ki ẹ mọ wipe aye si wa fun wa lati tẹ iwe awọn ọkawe ti nwọn ba wa l'Eko, Ebute-Mẹtta tabi Yaba ti nwọn ba ti le ṣe wahala lati mu awọn iwe ti nwọn ba kọ si Olotu na wa si ile iṣẹ wa ni 28, Kọsọkọ Street (ni adugbo ti awọn obinrin nta aṣọ loju gọta Ereko) L'Eko fun ra wọn.

OLOTU

---

# Awon Oga Ise 'Oni-wayo' Lugbadi Olopa Ikeja

IKẸJA—Awọn ọlọpa'nu Ikẹja wọ awọn ọga ile iṣẹ kan ti nwọn pe orukọ rẹ ni Llens Publicity ni ọna Agege ni Mushin ti nwọn ni iṣẹ wayọ ni nwọn nṣe nṣe wa si iwaju adajọ ni ijẹta wipe nwọn gba pọnuu marundinlọgọrin (£75) lọwọ awọn kan wipe awọn fẹ gba wọn sisẹ: Adesọla Ẹnilọ ati Chetu Ibegwaran ni awọn ọlọpa pe orukọ ọga ise oiwayo na.

Gẹgẹbi iwe ẹsun awọn ọlọpa lori ẹjọ wọn na, awọn enia meta Adebayọ Imoukhuede, Benson Fhomlas Sango — yemaye ati Mutiu, Abiọdun Shittu ni nwọn fi ọna eru gba owo lọwọ wọn wipe atike ati lọfinnda ni awọn nṣe ta.

Nwọn ni ninu awọn ti awọn ọdaran na gb'owo lọwọ wọn yi, awọn yio fi ẹnikan ṣe akọwe agbowo ile ise awọn awọn yio gba ọkan ni ọkọṣẹ atike ṣiṣe ti awọn nṣe ta nwọn ni awọn yio fi Abiodun Shittu ṣe akọwe atatiko ati wipe Yemaye ni yio ma ba awọn polowo ọja na kiri

Nigbati nwọn ka ẹsun wọn fun awọn ọdaran na nwọn ni awọn ko jẹbi rara. Awọn Ọlọpa ni ki Adajọ Kotu Ikeja na fun awọn nsu meji gbako ki awọn le bẹrẹ ro ẹjọ na nipu oṣu-kẹjọ (August) ti mbọ yi.

# Olotu Ijoba Apapo Ni K'awon Osise Pada S'enu Ise Won

EKO—Olotu Ijọba Apapọṣe ilẹ Naijiria; Alhaji Ọlọla Abubakare Tafawa Balewa, ninu ikede rẹ si gbogbo agbaiye ni ọjọ Aje (Monday) ti nṣe ọjọ kejọ oṣu yi, o kilọ fun awọn oṣiṣẹ pe ki wọn ki o padu s nu iṣẹ wọn lọgan.



Ọ'ọla Tafawa Balewa

Ninu ikede rẹ ti o sope lati ọsẹ to kọja ọpọlọpọ awọn ojiṣẹ ati oṣiṣẹ Ijọba, ti ile-iṣẹ ajọṣepapọu (Corporation), ati ti ile iṣẹ awọu ouisowo ni nwọn ti da iṣẹ silẹ patapata ati pe idi ti o fa idaṣẹsilẹ yi ni nipa pẹ ti Ijọba pẹ ki nwọn to tẹ iwe ipinnu tiwọn jade lori eto iwadi ti Ẹgbẹni Morgan ṣe lori ẹkunwo awọn oṣiṣẹ.

O tun sọ bayi wipe on ti ṣe ikede ọbẹ si awọn oṣiṣẹ kakiri gbogbo agbaiye lati le pada sẹnui ṣẹ wọn ki ijọba on le ni anfani ati le gbọ ẹdun ọkan wọn fun fun gbigbaro gẹẹl ofin, ṣugbọn sibẹ, on wa ri daju pe ẹbẹ ou ti kuna niwaju ẹwọn aṣiwaju ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ tobẹ gẹ e ti irẹwẹsi fi de ba iṣunna owo ilu wa, nitirona, fun anfani awọn oṣiṣẹ on bẹ wẹ wọn ati gbogbo awọd aṣiwaju wọn lati dẹkun idasilẹ yi, ki wọu si pada sẹnu iṣẹ wọn ni kiakia.

Siwaju si i, o tun fi nyeni gba ngba wipe Ijọba on ti ṣe ijiroro lori eto ẹkunwo ti Ọgbẹni Margan ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ ti ṣe lati ri pe ki idẹra wa fun owọu oṣiṣẹ patapata, ṣugbọn on ri wipe ẹkunwo ti o ba ju eyiti Ijọba ti pinnu le lori lọ yio ba ṣiṣun owo uina fun idagbasoke ilu jẹ eyiti Ijọba ti peṣe silẹ fun titi di ọdun mẹfa'

Ikede rẹ tun nfi yeni pe iwọnba owo ti o wa nipamọ nisisiyi jẹ eyiti a nilati ṣunna pẹlu ọgbọn lati le ni ọpọlọpọ anfani ni ayekaye oti fun ẹnikẹni, paapa julọ awọn agbẹ ti nwọn so ẹmi awọn ara ilu ro, ti nwọn si npese ohun jijẹ fun ọpọlọpọ awọn ti ko ri iṣẹ ṣe, ati wipe gbogbo awọn Ijọba Ipinlẹ ilu yoko ni awọn peiọ jirorọ lori ipinnu ẹkunwo na.

Ọlọla Abubakar sope on nireti pe gbogbo enia ni yio gbe Ijọba Apapọ lẹsẹ ninu eto wọn lati mu ki gbogbo nkan wa ni deede, bi o ti jẹ pe ijọba on yio kuna lori iṣẹ rẹ bi ko ba jẹa agbara lati tete ṣe idiua fun aiṣedede ati ibajẹ ti o le ba iṣunwoua ilu nitori idi eyi, Ijọba od ko le farada ira aye ti ilu wa nisisiyi lọ mọ nipa dida iṣẹsilẹ.

# Nihin Lohun Ati NibiGbogbo

### Lati Owe Ayiluka

**Ile Iwe Ofe:**

# Awon Obi Ti Nforuko Omo Sile Ni Ipinle Iwo Orun

Lati ipari oṣu ti o kọja yi ni gbogbo awọn obi ti nwọn nfẹ gran awọn ọmọ wọn lọ si ilẹ iwe ọfẹ ni ipinlẹ Iwọ Orun ti bẹrẹsi lọ fi orukọ awọn ọmọ wọn na silẹ gẹgẹbi ikede ti awọn alakoso eto ẹkọ ipinlẹ na na ṣe wipe ki olukuluku wọn tete forukọ awọn ọmọ wọn silẹ ki nwọn ma ba ri iṣoro rara.

Awọn alamojuto eto ẹkọ tun tẹnumọ ọ wipe ẹmọkọmọ ti a ko ba tete forukọ rẹ silẹ ko ni ri ile iwe wọu ni ọdun ti mbọ yi.

Nwọn tun sọ wipe awọn ẹbi ti o ba ti mu ọmọ wọn de ile iforukosilẹ kan nilati ri daju pe awọn gba iwe ẹri lati ọwọ ile-iwe na lẹsẹkẹsẹ

Ọga ile-iwe ti o ba kuna lati fun awọn ob ni ni iwe ẹri yi gẹgẹbi aṣọ; riu awọn obi bẹ ẹ ni ẹtọ lati tete mu ẹsun wọn wa siwaju awọn ọga ile iṣẹ eto nipa ẹkọ ti o ba wa ni agbegbe ibiti nwọn ba ngbe.

Nwọn tun ṣe kilọkilọ fun gbogbo awọn ọga ile iwe lati ri i wipe ṣe iṣẹ wọn pẹlu otitọ iru si awọn obi ọmọde niwọnyi gẹgẹbi ilana ti nwọn se s lẹ nipa eto ile-iwe ọfẹ na.

Ni aṣepari, nwọn tun kilọ fun awọn obi wipe wọn ko gbọdọ forukọ ju ile-iwe kan lọ.

## Olopa Mba Awon Janduku Sejo

ILESHA — Ninu irin-ajo ti Dokita M I. Ọkpara Olotu Ipinlẹ Ila Orun ati aṣiwaju ẹgbẹ ẹgbẹ Alakukọ ṣe si Ipinlẹ Iwọ orun ni ọsẹ to kọja, awọn ọlọpa mu mẹrin ninu awọn jagidi-jagan enia kan ti nwọn da ijọngbon silẹ ninu irin ajo nigbati o de Ilesha. Ẹsun wipe nwọn ba mọto ẹgbẹ Alaukọ jẹ pẹlu didi ti nwọn di ihamọra pẹlu aake ati awọn ohun ẹṣọ ti o lewu ni awọn ọlọpa fi wọn sun.

Awọn mẹta niuu awọn mẹrin na ni, Lamidi Agbaje, Adepọju Ogunjeyitimi ati Jacob Adekuibẹ, ni awọn ọlọpa mba ṣejọ lori pe nwọn ba mọto na jẹ lainidi, ẹnikẹrin Ogoọla Ọlagunju ni awọn ọlọpa ni o mu ohun ṣẹ lọwọ larin ilu lainidi lati da ibẹru ati hilahilo silẹ.

Ọlọpa ti mba wọn ṣẹjọ niwaju adajọ ni ile ẹjọ ibilẹ gi ni ilu Ilesha pe awọn mẹrẹ wọnyi ṣe ipalara fun Ọgbẹ Ọladipọ Famọriyu, Adebisi ati Sunday Ọlabinijọ, aw ọdaran na si ṣẹ kanlẹ awọn ko jẹbi ẹsun na nigbati nwọn ka ẹsun wọ na si wọn leti niwaju adajọ.

Ọga ọlọpa Ọgbẹni Babatunde Adeṣọla ni on lodi si i pe ki adajọ gba iduro wọn toripe ti adajọ ba gba idur wọn, sibẹsibẹ wọu yio tun ma yọ ilu lẹnu kakiri.

Lori ọrọ alaye ti ọga ọlọpa sọ yi, adajọ kotu Oloye Victor A. Ilọri gba si paṣẹ pe ki awọn ọlọp gbogbo wọn mole titi igba on yio tun fi raye gbọ ẹjọ wọn

**Awon Os'se Taku:**

# Ehingbeti L'EKoDabi Ite-Oku

EKO— Boya ọpọlọpọ ainu ẹnyin ọkawe wa ti de itẹ oku ni akoko ti nwọn ko gbe oku lọ sin sibẹ ri. Bayi ni Ẹhingbẹti, nibiti awọn Oyinbo onisowo gbe ti nta ọja lati ọjọ ti nwọn ti gunlẹ s'Eko ri lati ijẹrin ti awọn oṣiṣẹ ile iṣowo ti pẹlu awọn oniṣẹ Ijọba lati da iṣẹ silẹ lori owo oṣuṣu ti nwọn ni awọn alakoso Ijọba Apapọṣe fi kun owo awọn.

Oni ni o di ijẹtala ti awọn oṣiṣẹ Ijọba ile Nigeria ti da iṣẹ silẹ jakejado ni Eko, awọn oṣiṣẹ Agodi Ibadan ṣẹṣẹ ba wọn lọwọ si i ni ijẹta ni, A gbọ wipe la ia awọn akọwe Ijọba Iwọ Orun ko fọwọ kan iṣẹ ṣe rara, iwe irohin ni nwọn joko, ti nwọn nka, afi awọn ọga wọn ni nwọn sare soke sare sodo lati se iwọ iba iṣẹ ti nwọn e ṣe

nwọn ko ri aye gbowo ni Bank lana lati fi ṣe yọtọmi igbodun ipari oṣu ti awọn ara Eko ma nṣe lẹhan losu.

A gbọ wipe awọn ile ero gbohungbohun (redio) paapa ti faake kọ i wipe awọn ko ni ṣe iṣẹ. Lori ana ọpọ'ọpọ igba ni ero gbohungbohun nṣe segesege, ti ko sọrọ taara.

Awọn oni ana i ẹtiriki ti sọ wipe awọn kọ ni tanna fun awọn ara Ibadan Shagamu, Ikorodu Oshogbo ati Ijebu - Ode afi ti awọn alakoso Ijọba ba wo ikan ṣe fun ọrọ owo oṣu ti nwọn ni ki nwọn fi wo kun fun awọn oṣiṣẹ.

Awọn oṣiṣẹ Enugu paapa ti da iṣẹ silẹ pelu awọn ara Pọta (Port Harcourt) titi ti o fi de Kaduna.

## Ile Bank Tilekun

Gbogbo awọn ile ifowo pamọsi ni awọn awọwe ko fọwọ kan iṣẹ ṣe. Ni ara iwakati kan pere ni awọn banki pataki mọkanla ti o wa l'Eko fi ṣi ilẹkun fun awọn ti nwọn fẹ gba owo ati awọn ti nwọn fẹ fowo pamọ si banki na.

Ọpọlọpọ awọn enia ni

# Itan Oloyinmomo Fun Awon Omode

**Lati Owo D.A. Oyetoro**

Ni igba kan, Ọba kan wa ni ilu kan ti o fẹ lati mọ ẹranko ti o mọ o jọ julọ, pataki ijo Aro ati ṣẹkẹrẹ.

Ọba na wa ṣe ikede si gbogbo ọkunrin iju pe ki onikaluku wọn mu ẹranko tire wa eyiti o ba mu wipe o mọ ijo Ato ati Ṣẹkẹrẹ ijo, o si da ọjọ meje fun ere idije nla na,

Nigbati ọjọ na pe, ero lọ jara, awọn ẹranko ko jẹki a ri awọn ọmọ enia, gbogbo agbo nrọ gidi, ẹlomiran mu Ologbo wa, omiran mu ẹṣin wa, omiran si mu ekute wa ati oriṣiriṣi awọn ẹranko miran.

Ọba na si ti sẹlẹri pe on yio da ile ati ọna on si meji fun eniti ẹranko tirẹ ba mọ o julọ. Nigbati ọjọ kan na pe ti ilu bẹrẹsi dun, ekute lo kọkọ bọ sagbo, nwọn si nkorin, bai pe: 'Ekute lo mọ ijo aro jingimi o jo - kute - kute jingimi,, Aṣẹhinwa aṣẹhinbọ ekute ko mọ ijo aro ijo rara.

Aja Ologbo ati Ewure bọsagbo bakanna ṣugbọn wọn ko mọ Aro jo. Ẹṣin wa bọsagbo; ki ẹṣin to bọsagbo ni o ti nsọ ejika, ti iru rẹ nmi wuye-wuye bi irukẹri. Ara rẹ ti wa lọna.

Nigbati ẹṣin mujo jo Ariwo ta gee, ilu iluhọ ndun kikan-kikan Ọba paapa bọ sagbo ijo o gbe ijo wọ bi ẹwu titi ade ori rẹ ṣibọ sile gbogbo enia si bẹrẹsi jo pelu rẹ.

Nigbati ijo pari wayi ọba na wa paṣe ki ẹlẹṣin na wa si iwaju on larin ogunlọgọ enia pẹlu ẹranko wọn o si fun ni ọpọlọpọ dukiya gegebi ileri rẹ ẹlẹṣin na si di Ọlọrọ titi igbesi aiye rẹ.

Lati ọjọ na ni o ti jẹpe ẹṣin ni o jẹ ẹranko ti o jẹ ẹranko ti o mọ o julọ nitorina ni o se jẹpe on ni wọn imaa gunlọ si ibi ariya pataki.

**Ka oro ti Ojola Tafawa Balewa so lori ero Redio Iori Idase sile awon OSISE loju ewe Karun.**




# Irohin Eto Ikose

(O bẹrẹ loju ewe kẹ )

ti ko wasi irauti lati ṣe aṣẹwo nkan wọnni ti a ti fi owo ara wa ko silẹ.

Inu wa dun lọpọlọpọ lati ba ọgbẹni George Foggor pade, eniti nṣe oluranlọwọ fun iṣẹ pupọ fun iṣẹ ero ṣiṣẹ ti a ko le gbagbe lailai fun ọpọlọpọ ọdun ti o ti ṣe ni ilu Nigeria tẹlẹ ri gẹgẹbi ọga oludari iṣẹ ṣiṣẹ.

Gẹgẹbi gbogbo awọn ohun ribiribi ti a foju ri, ẹkọ pataki ti a kọ ati iwa ọyaya si enia lọnakọna lati ọdọ awọn ara ilu Gẹẹsi yi o fi han wa daju pe ilu Gẹẹsi jẹ ilu ti o tobi pupọ ju ti k ṣee foju kere rara.

Ki a to pada si ilu ti onikaluku wa ti wa a fi ọrọ iwuri dupẹ pupọ ọwọ awọn oluko wa fun iru eto ti awọn ati wahala wọn lori wa a si dupẹ lọwọ Ọlọrun ti o de ilu wa ni alafia pelu ẹrọ oriyeliye fi a ti ki, eyiti yio jẹ anfani fun awọn oṣiṣẹ ati Ijọba ile wa.

# International Affairs

LONDON—Dr. L. A. Fabunmi, Direcotor-General of the Nigerian Institute of International Affairs, spoke of strengthening the existing links between his Institute and Britain's Royal Institute of International Affairs, when he was entertained at a private luncheon held for him at Chatham House, London recently.

Dr Fabunmi is spending a week in Britain as the guest of the Commonwealth Relations Office.

Host at the luncheon was the Right Honourable Kenneth Younger, Director of Chatham House. Other guests included Mr Philip Mason, Director of Race Relations and Professor Kenneth Robinson, Director of the Institute of Commonwealth Studies at London University.

After giving a brief address, Dr. Fabunmi answered a series of questions about the Nigerian Institute and its plans for the future. Later he visited the British Society for International Understanding where he was received by the Director-General Mr John Eppstein who introduced him to members of the Society including two Vice-Presidents Major General S. Moore-Coultson, and Mr. Douglas Dodd-Parker, a former Parliamentary Secretary for Commonwealth Relations.

## Develop Taste For Cocoa Products Premier Inculates



### Chief S.L. Akintola, Premier Western Region

Chief S.L. Akintola, Premier, Western Region in speech to the masses of Nigeria generally and of Western Nigeria, in particular on the occasion of the opening of the epoch-making International Cocoa week on Monday, 8th June, 1964 at Ibadan, asked them to cultivate a taste for cocoa products.

Over the 200 cheering audience-among whom were leading Obas, Chiefs and substantial businessmen in the community-who had gathered at the exhibition site heard Chief Akintola saying "Cocoa is a nourishing food", which gives energy and vigour.

Chief Akintola further asked the cheering audience "Is vigour not our need ? Before the audience were allowed to answer the question, he gave a hint "If we do ingredients are sure to be found in the cocoa we produce. We must not yield all the benefits emanating from the production of the land."

## Nigerian Writes New Book:

### The Arrow Of God

LONDON— The impact of European ways on the old traditions of African society is a subject that absorbs many African writers. Chinua Achebe, the Nigerian novelist, has made it the theme of his first two books "Things Fall Apart" and "No Longer at Ease", and now his third book reflects the same concern.

Reviewing "The Arrow of God in the BBC African Service programme A BOOK FOR TODAY Ibrahim Tahir described how the hero, Chief Ezeulu, sent his son to the white man's mission to learn Christianity-or, as he puts it, to be his ear and his eye and bring back the secret of the white man's power.

'And, as in Achebe's first book said Tahir, things really do fall apart. For Christianity has no respect for the ways that Ezeulu exists to safeguard.' The son's new ideas split the tribe in two hunger and disease followed and old Chief went mad. Eventually the old yielded its place to the new.

'Reading the book, said Tahir' I was back in 'Thing Fall Apart. all over again, I missed some sign of the thunderclap of anger, the neathb ro wail of sadness the cock's crow of joy, and the chaos of despair. The madness of Ezeulu is tragic enough and Africa helpless and deranged while her children adjust themselves. The treatment of the story here, the celebral detachment that sees people as pieces in cultural chess game, smacks of an evasion that is embarrassing.

Nevertheless, Tahir considered that this was an engaging book and it held his attention. It has all the fine qualities of Achebe's writing the economy of style, the precision of language, and wealth of beutiful Ibo proverbs.

For World-Wide and Local News, Read Eleti-Ofe Your Yoruba Weekly Newspaper

# Olopa Mu Adamodi 'Oga Olopa' Kan

IBADAN—Ogbeni kan ti oruko re nje Emmanuel Ajagbe ni awon olopa mu ni ilu Ibadan lenu loolo yi nitoripe o npe ara re ni oga awon olopa o si nfi tipatipa bere owo kakiri lowo awon enia.

Awon ni adamodi oga olopa yi ko nise kan lowo ki o to lo gba okunrin alagbafo kan mu ni ojo Dugbe, eniti oruko re nje Okocha, eni odun marundilogta o si bere iwe owo ori re fun ti odun yi lehin gbati o ti sapyjuwe ara re gegebi oga awon olopa fun un tan.

Okunrin alagbafo na ko ri iwe owo ori mu jade lapo, sugbon o mu iwe eri isanwo ori jade (Tax Receipt) eyiti o ti gba lati ilu Ipinle Iwo Orun agbedemeji (MIDWEST) o si fi han oga olopa na pelu ele kiolopa na le jowo on lowo lati losi enu ise on.

Adamodi Oga olopa na faake kori o ni afi bi alagbafo na ba fun on ni poun meji-abo laisebe on yio mu de koto.

Aseninwa-asehinbo alagbafo na tun ni poun kan lori adehun pe ki oga olopa na kalo si ile on lati lo gba owo ti o ku sugbon ayo re di ibanuje nigba ti owo olopa tesnibe, ti nwon si mu lo lati baa sejo.

## Baba Onibanki Je Banki Lowo

EKO — Ile ejo giga kan ni Eko ti sun gbigbo ejo ti Ogbologbo Banki awon onisowo kan ti nwon npe ni Merchants Bank pe Ogbeni Patrick Osoba eniti o figba kan je alakoso Banki na si igbamiiran nitoripe awon iwe ile Banki-ti awon fe lo lori ejo gbese ie lori ejo gbese banki na ko si ni arowoto awon ti nwon pejo.

Ejo yi ti wa nile lati nkan bi odun marun sehin awon afunniso Banki Onisowo na fe gba Egbarafa ponun (£12,000) lowo Ogbeni Osoba eyiti o je owo-ele ti o ya pelu ele lori re ninu oso ti nwon fi pamo si Banki na.

Ni ojo Isegun ti nse ojo kesan osu yi, nigbati akowe kotu gbe ejo na siwaju adajo, Ogbeni Odesanya, ti o je agbejoro fun awon afunniso Banki na sope on koi ti se tan lati mu ba ejo na lo nitoripe awon iwe ti yio wulo nipa ejo na si wa lowo awon olopa, won ko si ti da won pada fun awon elejo ti on ngbe ejo fun, nitori idi eyi o bere fun atunsgbo ejo na.

## Agbawo Kan

(O bere loju ewe kinni) laipe yi ko le ise nla kan lori.

Gegebi a ti gbo irohin na nwon ni lati odun 1945 ti bale obinrin na ti jalaisi ni okunrin agboti yi ti nse amugba lehin obinrin na ti o si nse ike re lonakon, ob nrin na fi £500 sile fun iranse na.

## Bibelori Lo To Fun Amugbo

ABEOKUTA— Lenu loolo yi ni adajo kan, Ogbeni O. A Adeyemi ni ile ejo ti o gbe adajo ju okunrin kan si ewon odun meta nitoripe awon olopa ri taba igbo lowo re Abeokuta.

Okunrin na ti oruko re nje Erinmasa Olamide gba wipe on je bi ewon nini taba igbo lowo, o si be adajo pe ki o fi oju aanu wo on.

Gegebi oro ti awon olopa sofun adajo, nwon ni nigbati awon ri irohin gbo wipe Olamide toju igbo sile, awon ake re lati lo ye ile re wo, nigbati awon si de ibe, nwon ri opolopo eho igbo ninu ile re.

Ninu oro ti adajo so, o ni bi o ba sepe on lagbara re ni, on iba pase pe ki awon ki o ma a be enikeni ti o ba nmu igbo lori nitori taba buruku ni nse.


## TRADITION REFLECTED IN PROGRESS

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23370; Editor, (Olotu) Ola Onatade 15, Kosoko Street, Lagos, P O 467, Lagos.